The Chief Secretary to the Govern


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. II. No. 82 SATURDAY, FEB. 2, 1924. FOURPENCE.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA.)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

**"Specialities: Enamelware, Beer, Wine, Iron Bedsteads, Ruby Plates, Rubber Beads of all kinds, Clay and Briar Pipes, Champagne, Cement, Biscuits in cases, Gun Powder, Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice, Accordeons, Piano, Padlocks, Beads, etc., etc., etc."**


**Circulation 1,000 Copies Weekly.**

ẸGBERUN IWE-IROHIN YI LA NTẸ LOSOSẸ.


## N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laifai, l'eti *Glover Memorial Hall, (Customs Street,)* EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ransẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirișì Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja abọmafọ ati orișirișì ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

**J. C. VAUGHAN**

Ti Ile-Qja Shefield ni Ilu Kakawa ati Ile-Qja *Excelsior* " ni Ita Agarawu, ni onruru awon ohun ekole fun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nsowo Irin Ise lorisirisi lati adota odun sehin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni OGBENI na je ninu awon onisowo Irin Ise ni ilu Nigeria.

OKO tita wa ni owo po o.

Cable Address :— "Steinafrik" HAMBURG.

E. H. STEIN & Co.

HAMBURG, Neurwall 16/18, Hildebrandhaus.

AFRICAN MERCHANTS.

ALL INDENTS EXECUTED.

for

English and Continental Goods

and

PRODUCE

Sold on Best Terms.

Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.

P. O. Box No. 505.

Agent in Lagos :—

Mr. Karimu Kotun

Broad Street, & Portonovo Market Store.

**B. O. Joseph**

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**

**Sundries.**

**Hardware.**

**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

ENIKEJI,

Aso Oke to yanju mbe lodo Iya Afin Saamota Ike Olorun fun tita, opoku Oyoku ni owo won, lo bere ni 3 St. John Street, l'Eko, leti ile Johnson Agbejoro.

## BULL WEST AFRICAN LINE, INC.

AWON OLOKO TI IJOBA AMERIKA

Oko elefi awon Oyinbo wonyi nko ero ati eru ni Iwo Orun Afrika, ni ososu o si ngba ero lo si ilu Amerika ati awon ilu miran pelu. Oko won yara, owo po ni nwon si ngba. Enyin ero, enyin onisowo Obi, Koko, Ekuro ati Epo, e lo ke si asoju awon Oloko yi ni — Oke Pelesi ile *Colonial Bank*, ni Ehin Igbeti, Eko.

## ERO YA WA RA.

ADEBOYE SOLANKE Onisowo "Gbabiogede" ni Panu-kikole ati kikan-oko, Ileo lorisirisi, Kokoro (Isika) t'ilekun ati t'apoti lorisirisi, Atupa fifalowo, Simenti, Oda lorisirisi ati Epo-oda, Fikifiki, Okun-ero, ati Osan, ati Pakun ti Awo-eja lorisirisi, Awo ti awon Aganyin fi nko Eja-sawa l'okun ati Eja Abomafo, ni Ile-oja re ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Mo'oney Bridge Street, (l'Anikantamo) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-ise Agbede Iworo ati Fadaka.

OWO OJA RE FANIMORA.

E LO RA TIYIN NIBE.

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Offices* : 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RẸ

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

BI ERE BI ẸWA, ỌDUN IPADE IJỌ TUN YI DE, A YIN OLUWA !

Awọn Ijọ *Wesley* bẹrẹ si Ipade Ajọdun wọn ni *Church* Ita Tinubu ni *Thursday* (Alamisi) ọsẹ yi a ki awọn ẹni wa na ẹ ku ewu oṣu mejila to ti rekọja.

EGẸ YẸ Ẹ, AMỌLẸSẸ BI IYAWO, ADỌGBAJALẸ OKỌNRIN.

A gbọ pe *Archdeacon* T. A. J. Ogunbiyi, Alufa Ijọ Onidunkun Oyinbo, yọda *Church* kekere ti o kọ s'eti Itẹ-oku ni Ikoyi fun awọn Ijọ *Wesley* lati ma sin nibẹ nitori gbigba ti Ọba ti gba *Church* awọn Ijọ na eyiti nwọn kọ si oke Ikoyi ri (ki ṣepe Ọba jagba lọwọ wọn ni o, bikoṣepe Ijọba sanwo fun u; aila ọrọ, lo p'Elenpe iṣaju ti o wipe igba wiwo j'awo lọ; ẹla lọrọ) awọn Ijọ yi npete ati ṣe Isin ninu *Church* na lọla.

*Archdeacon* Ogunbiyi, iwa yi wun wa o!

ẸNYIN MUSULUMI EKO, Ẹ DÁKẸ NI ?

Riri ti a ri Imale ọrẹ wa kan ni lọlọyi, pẹlu ọmọ rẹ ọkọnrin lọdọ wa lati wa ṣaroye pe gbogbo Ile-iwe-giga Eko lo kọ lati gba ọmọ on si'le iwe nitoripe o jẹ ọmọ Imale mu ki ẹkun ko gbọn wa nigbati a ri pe baba ọmọ yi ṣe wahala kita pe ki a le gba ọmọ rẹ na, ṣugbọn sibẹsibẹ ti a kọ ọ. Ẹnyin Imalo Eko, ẹ dide si ọrọ Ẹkọ fun awọn ọmọ nyin nipa kikọ Ile Iwe Ẹkọ Giga ati wiwa Olukọ fun wọn. Ẹ ko ri bi Iwe-mimọ ti yẹ Omidan Awawu Thomas to nijọsi nigbati o fi nsọrọ rẹ lede Gẹsi to jafafa ni Kõtu nigba ẹjọ rẹ pẹlu Alaji Salusi ti Lafiaji lẹnu ọsẹ diẹ yi ?

Agba dọwọ nyin o !

ENYIN NI ẸNIT' O MBỌ, TABI KA MA RETI ẸLOMIRAN ?

A gbọ pe Ijọ St. Peter fi wiwa ṣiṣẹ larin wọn lẹhin "iṣubu" Alufa J. A. Cole, lọ Alufa C. Doherty ti *Church* Kudẹti ni Ibadan, ṣugbọn Alufa na kọ, a si tun fi Ijọ na lọ Alufa Alabojuto S. C. Phillips ti Ode Ondo, ṣugbọn o tun kọ bakanna ; a sọ pe Alufa Latunde Oloye B.A. ti Ogbomoṣọ ni "ẹbọ" awọn Ijọ na ṣi tun mu nisinsinyi.

ỌRAN ỌMỌ JA-NTO JA-NTO !

Iṣẹ gbe wa lọ si Ibadan ni *Monday* (Atini) ọsẹ yi, bi a si ti wọ ọkọ-ilẹ ti a de Ibusọ Alagbado, bẹni ọkọ ṣi mọ Abiyamọ kan lẹsẹ ti ọmọ rẹ wa ninu ọkọ: ki ẹ wa wo iwara-papa, igbaraṣanlẹ obinrin na ti o tẹ fo mọ ọkọ nigbati o ti ṣi, lọgan Ọga Ibusọ ibẹ (*Alagbado Station Master*) si di lọwọ mu gbagi ki ọkọ ma ba tẹ ẹ rẹ : nigbati ọkọ de ibiti o jinna to lati *Office* wa de ti Tika-Tore ni apejuwe, ni ọga *Station* na ṣe apẹrẹ dida ọkọ duro si Amọna ọkọ (*Train Guard*) na ti o njẹ Z. O. Sọnya lọgan ọkọnrin oninure yi si ju asia rẹ si Awakọ (*Driver*) wàrà-were bẹni ọkọ si duro ; ki ẹ wa wo bi a ti nsare wayi, atẹlẹsẹ obinrin abiyamọ yi fẹrẹ ba ni ipakọ nigbati o nsare, ti o si nmi hẹlẹhẹlẹ, ọran ọmọ ko ṣa ri bẹ, eyiti a nwi yi ti pẹ bẹni awọn alami miran mba sare ti nwọn si ti sinu ọkọ; bẹni ọkọ si tun gbọn ire si i, ti o nlọ bi ẹfufu, obinrin na bẹrẹ si kunlẹ dupẹ lọpọ-

lọpọ lọwọ Ọgbẹni Z. O. Sanya na ati lọwọ igbakeji rẹ Seidu, ati lọwọ Awakọ ati gbogbo enia to bi ṣãjo nigbati o njowere ki a to da'kọ duro fun u.

### SHITU BALẸ, E KU EWU ỌDUN.

Awọn ara Ibadan ṣe ọdun Oke Ibadan wọn ni *Tuesday* Atalata ọsẹ yi; gẹgẹbi aṣa wọn kosi ẹniti o dana ni igboro tabi ti o na ọja, nṣe ni gbogbo Ilu nho gẽ ti ijo gbojikan larin t'ọkunrin t'obinrin ere gbode lati arọ di alẹ, ọrọ ti nwọn si nsọ lẹnu le di enia leti; o si jẹ irufẹ eyiti bi ẹnikẹni daba ati sọ l'Eko nibi, m'ọwọ-m'ọrun ni Ọlọpa yio mu oluwarẹ; nitotọ Idalu ni'ṣelu.

### AJEJI TO F'ORU WỌ'LU, IGIDA NI YIO JẸ!

Nigbati a de Itori ni lilọ si ajo wa ni ọkọ wa f'ẹnu gbunlẹ, a si ni lati wa nihin bi wakati meji-abọ ọsan *Monday* a si wọ Ibadan ni agogo mẹsan oru Aburo wa Ọgbẹni A. M. Suberu, Aṣoju (*Agent*) wa ni Ibadan fun tita "Eko Akete" para para ni *Station* Ibadan lati pade wa titi ọkọ fi de ti o si mu wa lọ sile ni agogo mẹsan oru nigbati a gunlẹ, ọpe lo yẹ aburo wa yi Suberu Abogunloko Ejigan inogun. A si dupẹ lọwọ I y a w o rẹ Mrs. Francisca Suberu fun itọju ati igẹ wa.

### MRS. SANTOS, O KU AFOJUBA.

Iya afin Mrs. Santos ni o kọkọ wa ki wa kabọ 'nì alẹ *Monday* na pelu awọn ọmọ rẹ ọmọdan Santos, ọmọ ologbe Q. B. Santos tayọtayọ ni nwọn si fi ki ni, ko pẹ ti awọn ọmọbinrin na pada bọ wa'le lati Saro nibiti nwọn gbe ti lọ kọ'we, lẹhin iku baba wọn Q. B. Santos Ajiṣefinni. Ki Ọlọrun f'ọrun kẹ!!!

### "SARI TO, Ẹ DIDE Ẹ JẸUN."

Ipade gbogbo-gbo ti Ẹgbẹ Tunluṣe wa lọsan yi ni Ile Afari Ogun l'Ẹhingbẹti l'agogo mẹrin. Ki ọmọ Ẹgbẹ kan ma ku lẹhin lati wa si ipade ribiribi yi. A gbọ pe ojulowo ọrọ wa ti a o sọ nibẹ.

### RUKERUDO DE, RUKERUDO DE!!

A gbọ pe ija kan bẹ silẹ larin awọn ara Ilu Nsuka lagbegbe Onitsha ati awọn abi sokoto pọnbe tobẹ ti a fi sọ pe awọn Ibo ara Ilu na fi pa Oyinbo Ọga Ọlọpa kan ti o njẹ *Major* Rew Castle ija yi gb'ọwọ tobẹ ti ijọba fi ran awọn Olori Ọlọpa ati awọn Ọlọpa lọ si ibẹ ni lọlọyi.

### ẸJỌ TUN SUN NI GANRAN!

A gbọ pe Igbakeji Adajọ Agba tun fi ẹjọ awọn Imale si ọsẹ to mbọ ni arọ ana.

---

Si Oni'we-irohin "Eko-Akete"

Mo juba o,

Lati bi oṣu melo sẹhin ni mo ti nwo bi nkan ti nlọ, njẹ ki nto fi ẹnu le ọrọ diẹ, mo ki t'ọkunrin t'obinrin E ku ọdun E ku iyedun.

Ninu ọdun to kọja a ti ri onirunru ohun ribiribi to ṣẹlẹ, awọn bi melo kan ti fi ẹsẹ sẹ ninu awọn Alufa Onigbagbọ, awọn Oniṣowo ẹwẹ ti ri ohun ti oju wọn ko ri ri, ẹniti o ba tọ wo lo mọ pe iyọ dun.

Awọn oṣiṣẹ ẹnikẹni le jẹri pe Kapinta di Lebira Erin omi di Erin oke, ọgbọn jamba ndagba ninu onikaluku, ọrọ Eleko njẹ t'ọmọde t'agba l'ọkan. Ki Baba ma ṣai gba ajo awọn majẹ-ko-bajẹ.

Awọn Oyinbo Ọlọkọ (*Elder Dempster & Co., Ltd.*) nṣe bi arira. A ko le fi oju fo Ọgbẹni wa "ọmọ Oujaiye" E. Alao Ojo ẹniti o jẹ pe iṣẹ owo sisan lo nṣe fun awọn Oyinbo ọlọkọ wọnyi lati ọdun mejidilogun sẹhin, eyi fi han ni pe suru ati iwa rere lẹṣọ enia, awọn baba wa a ma pa ni owe pe "bi egun ẹni ba mọ jo ori a ma ya atọkun rẹ" njẹ OJo Yẹwugẹ Alagada-ogun a nreti awõwõ wurujẹ o.

Ninu ọdun titun yi ẹwẹ ailelẹ ọkan nba wa ja nipa onirunru jamba iku ojiji ti a ngbọ ti o si nṣẹlẹ lojojumọ, ki Oluwa fi iṣọ rẹ ṣọ wa.

Inu wa dun fun iro ti a gbọ nipa ti awọn ẹbi Ọlọtọ nipa fi fi oju sun Ọgbẹni wọn kan fun a r o l e ninu I g a wọn, adura wa nipe ki Oluwa ma ṣai ba wọn yan ẹni rere sinu Iga yi. Iga miran ti a tun gbọ ni ti awọn Olumẹgbọn, Iga yi jẹ Iga pataki ati pe o si jẹ olori fun awọn Idẹjo, a gbọ pe awọn ẹbi ninu Iga yi ngbero lati mu Lawani Kuṣemi ọmọ Saloriṣa fun arole. Ẹnikẹni le jẹri pe Kuṣemi yi jẹ oninututu enia ati pe ara rẹ gba oniruru iwọsi, o si ja fafa pupọ, ati pe lakaye rẹ si pe. Ki Oluwa ma ṣai tun Ilu wa yi ṣe fun wa. Awọn Ẹfẹ ma nkọ'rin pe:—

"Eko şi ma jẹrọ bopẹ" njẹ Aromirẹ, Onitana, Eletu Ijẹbu, ati ẹnyin Iga miran ẹ ma ma jẹ ki oro pa le nyin lori.

A ko le şe alai fi ẹnu kan ọrọ awọn Imale wa lode Eko yi, ọrọ wọn sati di ajaku-akata. A gbọ pe ọro Ọlọrun ko mu'ja wa, şugbọn ti Eko wa nibi mu kunmọ, ọgọ, ada, ati gbese dani.

Emi ni ti nyin ni gasikia,

AKIRIMANU.

## FACTS AND FIGURES

### RADIOPHONE CURIOSITY.

**Television, Another Possible Scientific Invention. Seeing Wimbeley From Lagos !!!**

To make a telephone call upon a friend or a business man at Agege and indulge in a lively conversation in the ordinary way is wonderful enough. To receive a cablegram sent from London, Lisbon or New York this morning is also wonderful enough. But to converse ordinarily with someone at Zaria, Freetown, Port-harcourt or any of the places mentioned above, or, still, to hear people sing in those places is the greatest miracle ever wrought by modern science.

It is Radiophone, the most wonderful development in modern days' message transmission. Considering the immensity of works this strange instrument does it should be noted for its simplicity of construction. You simply want to buy a good set and have it duly installed in your house. There is the Broadcasting Station (a sort of Exchange Office) where you can be put through and without "much ado" you may speak to or hear people speak or sing in any place on land or accross the seas according to the Broadcasting Programmes—may be Jerico or Green Land's icy mountains.

In progressive counties at present Radio is the "Thing" and in all probabilities Nigeria, or rather, West Africa, may, in these days, add her own share to the daily increasing world of Listeners-in.

One is much more impressed by the change, the great change such message transmission process is likely to make in modern civilisation and the world at large. The cause of education could be greatly furthered; for, among other ways of imparting education, lectures on academic and general intellegence could be heard from the farthest ends of the earth.

Trade relations could be much more improved by means of easy and cheap international communications.

The theatrical world will enjoy much more popularity; for, vocal concerts could be enjoyed at your own home and while you can hear the greatest world tenor you also can dance while the world's best orchestra plays from thousands of miles away.

Radio sets could be got in portable forms and could be carried about in cars and other vehicles. "Further," says A. B. in an article published in *The World To-day* for December 1923, "all the while new usages for broadcasting are being developed. Frame aerials are being fitted to Pulman cars and to touring motor cars. Political and other oratory is being broadcasted more and more. Portable Sets with loud Speakers, capable of being heard over distances up to a mile are delighting country side gatherings and even replacing at times the bands in some of the provincial parks. The police, the hospitals and other institutions have found again and again that broadcasting organisations are of value to them

Everywhere radio is opening new roads to the dissemination of knowledge, and to an increase of the amenities of life. Undoubtedly radio is going to be one of the biggest factors of improvement in the world as well as one of the biggest industries."

The following appeared in the Reuter's Telegrams for January 8:—"Colonel Malone, the Chairman of the, Radio Association, in an interview on the recent transmission of American broadcasting by a British broadcasting Company, predicted that 1924 would see *television, i. e. seeing by wireless,* practically within the bounds of possibility." We rather should leave our readers to imagine a world in which for instance one can remain in Lagos and look at Wimbeley and see the Empire Exhibition in progress with almost as much facility as the people on the spot.

ADEKANBI.


**FRIENDS and COUNTRYMEN,**

**LET US SEIZE THE OPPORTUNITY OF THE DAY.**

Become a certified Medical Herbalist and learn how to alleviate human suffering by the skilful use of

***NON-POISONOUS HERBAL REMEDIES.***

The British College of Herbal Medicine of Bolton, England, prepares students to qualify as certified HERBALISTS by studying their Correspondence Course of Lessons.

For full particulars, apply to the Official Representative of the College :—

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos, Nigeria, W.A.

Remember that :—

*The more you know, the more you know how little you know.*

**Ile Ita Egbogi ti Macaulay,**

88, BROAD STREET.

Wabiwọsi orişirişi Egbogi lo şẹşẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orişirişi, ogun Ẹda, ogun arun aşiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbameji, ogun Aran orişirişi, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wọnyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday, February 2, 1924.

### ARA ILU, Ẹ GBARADI:
### A KÌ TI JỌ OGUN W'ẸFỌN.

Ni ọsẹ tokọja, a sọ fẹnrẹn pe awọn Agba diẹ ti Ẹgbẹ *Congress* mbọ lati Saro ati ilu Aganyin fun ati wa bẹ ibi wo nitori aibikita ti Ẹka Ẹgbẹ na ni ilẹ yi: o ti le ni ọdun meji nisinsinyi ti Ẹka Ẹgbẹ yi ti ṣe Ipade rẹ ikẹhin: a si mọ ikunsinu pupọ to wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ nitori ilọwọwọ ẹgbẹ na: o jẹ ohun ti o bu enia pe bi ẹgbẹ yi ti nlu gbàgbà to ni ninu ọdun 1919 titi de ọdun 1921 tokọja ofo lo gbẹhin rẹ!!! Ṣugbọn bi a ba da silẹ ti a ba ṣa a, a o ri pe awọn ọmọ ẹgbẹ na ko ni ẹbi kọkan rara; o ni ipa ti Oluwa Oloye sa, o ni ipa ti Ọgbẹni Herbert Macaulay sa, o ni ipa ti J. Egerton Shyngle Ọlọla sa, o ni ipa ti Ọgbẹni L. A. Cardoso sa, o si tun ni ipa ti Alufa Patriarch J. G. Campbell sa, ati awọn jakan-jakan miran pe ki atupa Ẹka Ẹgbẹ yi ma jo, ṣugbọn pabo ni; nitoripe iwa ko jẹ eku, ko jẹ ki eku jẹ ti o wa lọwọ Sẹkitẹri Ẹka Ẹgbẹ na lo mu Esekoyi-ana wa nilẹvi.

Ẹnyin ara wa yio ṣakiyesi pe Ẹgbẹ yi ni Oluwa Oloye ati Ọgbẹni Shyngle Ọlọla ṣe oju rẹ ni Ilu Oyinbo ni oṣu *October* ọdun 1920. Ẹ o si tun ṣe iranti pe ijakuakata ti Ẹgbẹ yi ja ni ilu Oyinbo ni ọdun na, lori ipinnu iyeṣiye ti Ẹgbẹ na ṣe ni Ipade gbogbogbõ ti a ṣe ni *Accra* ni oṣu *March* ọdun 1920 lo fun wa ni ohun ribiribi ti nini anfani ati yan aṣoju wa sinu Ajọ Igbimọ Aṣofin ti *Nigeria* eyiti a ṣe ritiriti rẹ ni oṣu *September* tokọja.

Nigbati awọn Ẹka Ẹgbẹ *Congress* na ti Saro ati ti *Gold Coast* si kọwe si awọn isọri isọri ilẹ yi pe nwọn mbọ wa lati wadi ifasẹhin yi, o yẹ, o si tọ jọjọ fun tolori telese wa lati bẹrẹ si jiroro ọna ti o wọ ti a o fi gba awọn Ọlọla yi—Awọn Ogunnagbongbo Ọlọla Mayor C. May olori Ijọ Munisipa ti Saro, Ọlọla T. Hutton Mills Agba, *Lawyer* af'owo-ṣe-ilu-lore, Ọlọla Casely Hayford Oloye M.B.E. Amọroro, Aṣelẹbẹ Koro, Ọgbẹni Samuel Richard Wood Sẹkitẹri—tọwọ-tẹsẹ: nitotọ ni owe wa kan sọpe agba ki iwa lọja ki ori ọmọ titun ki o wọ́, a si dupẹ pe awọn Alagba wa yi ni ifẹ pe ki imọlẹ ti Olodumare papa f'ọwọ ara Rẹ tan fun gbogbo ilu t'o wa labẹ asia Ọba *King* ni Iwọ Orun Afrika ni ọdun 1920 nipa di'a ẹgbẹ nla na silẹ ni Accra ni 1920, ki o maṣe ku, lo mu ki itara awọn enia wa wọnyi pọ tobẹ lati wa ṣe atunṣe ti a wi yi ni arin wa.

A o ma sọ igba ti nwọn yio de sibi nigbati o ba ṣe: ṣugbọn ihin yi ko di awọn ilu lọwọ lati pobirikoto ati ma ṣe imura silẹ diẹdiẹ titi nwọn yio fi de.

O d'ọwọ nyin o, A mu lele!

---

**STOP PRESS!!!**

**Death of Mr. Herbert Akinrinde Macaulay.**

A cablegram announcing the death in England of Mr. Herbert Akinride Macaulay, at one time a draughtsman in the public service in this place, and a prospective law-student and younger brother of Barrister Orunmakide Macaulay's of Calabar Lagos Bars, was received here by the family during the week.

This is the first time, as far as we know, in which a Lagosian or Nigerian, for that matter who left home to prosecute the study of Law, received his last summons for the Courts above whilst in Europe.

Our Condolence to the bereaved family.

**Impending Arrival of our Muhammadan Lawyer.**

Mr. Lawal B. Augusto Barrister-at-Law will sail for his return home on the 6th instant; his arrival is therefore expected on the 21st or 22nd inst.

---


**CHANGE OF NAME.**

I the undersigned formerly known and addressed as

TIAMIYU ABIODUN LAWANSON

of 2, Hotonu Street, Lagos, Nigeria, hereby beg to inform friends and the public in general that on and from the 1st day of February, 1924. I desire to be known and addressed as.

THEOPHILUS ABIODUN ONITIRI

All documents bearing my former name remain valid.

*17th Jan, 1924.* T. A. LAWANSON.

# ILE IFI ỌJA AWỌN ENIA PAMỌ SI LAILEWU.

Nigbati Ọja rẹ ba de lati Ilu Oyinbo, ti o si ni ẹ lara lati san owo Ibode lori wọn, awa yio ba ọ gba Ọja na, a o si ba ọ ṣe opo iwe gbigba wọn ni'bode.

Ti o ba si fẹ gba Ọja rẹ na lọwọ wa, iwọ maṣe ṣopo ati gba gbogbo wọn lẹkan bikoṣe eyiti ipa rẹ ba kọkọ ka na lati sanwo 'bode fun.

Iwọ yio ri pe ọna yi na ẹ lẹhin ju pe ki o lọ t'ọrun bọ igbese lọ!

Ẽra ko ni ra Ọja rẹ na ti o wa ni itọju wa.

Abẹ abo Agbowo-ode Ọba ni ile Ifi oja awọn enia pamọ si lọdọ wa wà.

Igbakigba ti Ọja rẹ ba tun de, ti owo ba si pọ lọwọ rẹ lati gba wọn, sa lọ ri Ọgbẹni yi:—

**JAMESON,**

Ni Opopo-nla,

Leti Ile Dr. O. Sapara, I.S.O

l'Eko.

# ERVEN LUCAS BOLS

## AMSTERDAM

## 1575

Whenever you see the word

# BOLS

It means a reputation of over 300 years.

***Bols very old LIQUEUR GIN is the Gin for the man of good taste.***

**STONE JARS AND GLASS JARS**

**5s.** per Bottle

***FROM***

# GRACE BROS.

— ***DRINK IT NEAT.*** —

## JANUARY

TABI

## OŞU KINI NINU ỌDUN TITUN.

[ *Lati ọwọ* ATARI AJANAKU. ]

Si Oni we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f'oji,

Ohun gbogbo li o ni ibẹrẹ ati opin; bi o si ti wa li atetekọşe, o nbẹ nisisiyi, bẹni yio si ma ri titi aiye ainipẹkun.

Ọdun 1923 ti kọja lọ pẹlu gbogbo wahala, iponju ati airikan-şe-kan rẹ; ọpọlọpọ enia li o si ni ireti wipe Ọdun titun ti a bọ si yi, yio jẹ Ọdun rere: şugbọn ọkan awọn ẹlomiran ti o mọ itú ti "Leap Year" le pa, ko balẹ si ireti na. O jọ gàté, ko jọ gàté, o dabi ẹni wipe Ọdun yi fẹ fi ẹsẹ mejeji tiro.

Lati ọjọ kini oşu January titi o fi pari ni ijẹta, enia melo ni nkan ha ti i şe gbẹdẹ fun, enia melo ni o ha ti i ri afo ati bọ ninu gbese, enia melo ni o ha ti i ri işẹ şe ninu awọn ti ọdá işẹ da? Bi a ko ba ni tan ara wa jẹ, ode na şi le sibẹsibẹ—ọpọlọpọ enia, enia pataki l'ọkunrin, l'obinrin, l'ọmọde, l'agba ni a si ti igbe sin li ọjọ aipe. Bi otutu lasan mu enia, ki o to to wakati mẹta li ẹhin na, o di ki a ma sare lọ si ile Onişegun; a-sin-wa-a-sin-bọ, iku oluwarẹ na a sọ Dokia di eke, a sọ Babalawo di ọgbẹri.

Nigbati enia ko ba ni owo l'ọwọ, ti gbese yọ gògóngò si i l'ọrun, ti ko ni işẹ l'apa, ti ko ni àbọ l'ẹsẹ, ti ọ̀fọ tun wa nşẹ ẹ, ti o ni lati sure lọ si ọdọ Sule, tabi Anthony, tabi Cole lati lọ gba awin Posi; ọran oluwarẹ ko ha di ti "Ko si alabaro" baun? Bi enia ba si jàja ni owo l'ọwọ diẹ, ti ailera diẹ kọlu u, adura ki o sa le ku şa ni ẹlomiran ninu awọn ọmọ rẹ yio ma gba, nitori a ti ri ogún jẹ—ọpọlọpọ si ni irufẹ awọn ọmọ bẹ, ti o wa ni ipo "A-gb'oju-l'ogún fi ara rẹ fun òşi ta" loni.

Njẹ mo bere, kil'o tilẹ nmu inira ati ibajẹ po li arin wa? Nigbati Alufa Şọşi ti nja Ọlọrun l'ole, ti Alufa nmu ọti a-mu-para, ti Alufa nlé'mu kiri bi Obukọ, ti ilẹkun Mọşalaşi ti nitori ọ̀tẹ, ti awọn Mọşàşí ati Sondókò nfi ọba Eleko ta'hín, ti a nrin ni ilẹ ti inu nbi Ẹlẹşin, ti ọmọ oni'lẹ ntẹ ẹ jẹjẹ, ti ajeji ntẹ ẹ girigiri, ti ọmọde nşe afojudi, ti agbalagba nhu iwa a-d'agba-ma-da'nu, ti alayinsi ko jẹ ki ọrọ pari, ti awọn obirin nşẹ'wó kiri, ti ko si ibẹru Ọlọrun, ti ko si ojusaju enia, a ko le fẹ ohun ibanujẹ kù ni ilu; nitorina, Ẹnyin al'aiye, ẹ lọ tun aiye şe, Anabi Isa nd'ẹhin bọ.

Ki Ọlọrun şe eyiti o ku li ọdun yi ni rere fun wa, ninu ofi, ninu ọlà, ni ọmọ pandoro ngbo si.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI AJANAKU.

## ISIN IKORE ATI ISỌJI

NI

## IJẸBU-ODE.

IV.

Ni agogo meji-abọ Monday, awọn ẹgbẹ Onişegun (*Native Herbalists*) şe apejẹ nla fun Olulana lati fi ayọ wọn han fun wiwa rẹ si Ijẹbu Ode. lẹhin ti a kuro ni ibi apejẹ, Ijọ pataki (*Native Sacred Dance*) wa fun onile at'alejo (*Members and Non-members*) lati fi han bi inu wọn ti dun to fun wiwa "Bishop" sarin wọn ati işiri işẹ nla ribiribi ti o şe larin wọn, ati lati şe ibosẹ Isin Isọji ati Ikore. Alli Mabinu si fi awọn orin pataki kan sara si "Bishop" fun imọyi işẹ rẹ larin wọn. Irohin ko to alọju ba; ere na dun pupọ. Mukẹ ni awọn obinrin nbujo mọra, aşọ oke npe aşọ oke ranşẹ, "efin-niwa" ko jẹ ka ri "ape adirẹ;" nkan şenure. Ere na pari niwọn agogo meje alẹ.

Niwọn agogo mẹsan Tuesday, Olulana rin ilu wo, ati lati lọ dupẹ lọwọ awọn ara ilu gbogbo ti nwọn nọwọ, ti nwọn si nwa şe ayẹ-i rẹ lati igbati a ti de ibi, a dari wale niwọn ago kan gan. Ni owuro kutu hai Tuesday na ọkan ninu Olukọbinrin ti Ijọ wa wa li ayọnu ara rẹ lati dapọ mọ Ijọ; Olukọ na ni Miss Bernice Ẹrufa, o si jẹ akikanju Olukọ'binrin gidigidi, o si jẹ onisuru ati ọloyaya omidan; adura mi ni pe, nipasẹ rẹ ki ọpọlọpọ awọn omidan ẹgbẹ rẹ di ero inu Ijọ wa. Aşẹ. Amin o. Aşẹ.

Ni Wednesday, a fi ẹsẹ ba gbogbo ibiti o kù lati de, a si pada wa si ile ni iwọn agogo meji. Ki l'a wọ ile si ni, enia ti nrọ wa, fun oniruru ikan-kojọ-kan; omiran fun alaye, omiran lati fi oruko silẹ, omiran lati jẹwo otitọ yi ti o wo ilu won. Ọpọlọpọ li o si ba ara rẹ tanma lati dapọ, ati lati ni ọwọ ninu ohunkohun ti Ijọ na ba dawọle lati şe laipẹ. Ki a to fi oju ba orun ni ọjọ na to iwọn agogo mejila koja; oşupa ọ̀jọ na buaiya, o de góngo.

Ni wẹ̀rẹ́ owuro Thursday, ni waraşẹşa, a ti di ẹrù wa jọ, a nreti Mọto ti yio nu wa wá si Ejirin. Ki o to to iwọn agogo meje-abọ, ẹsẹ awọn ọmọ Ile-ẹkọ wa ti pe şiba, gbogbo won li o tọlọnjọ ara, oju wọn si gún régé; kini nwon wa şe? Nwọn wa lati paşẹ, ati lati dagbere fun "Bishop" Brotherhood. Gbogbo wọn si tò ni mejimeji wa si Oyingbo (Ijẹbu Ode.) Nigbati awa papa ma fi de Oyingbo ninu Mọto ti a wọ, ero ti pe biba de

wa nibẹ. Bi Ọba nlọ ni ilu, tabi nlọ si ajo, ko gbọdọ to bẹ yẹn; anu ṣe mi wipe irohin ko to afojuba. Ọjọ nla, ibukun ọjọ li ọjọ na jẹ. Ọjọ ti o ju ọjọ lọ fun Olulana ati Ijọ Ijẹbu Ode. Ẹsẹ ero Ijọ ati awọn ara ilu pe. Awọn ti koi ti ni anfani lati mọ Olulana nnaga lati mọ ọ. Nigbati awọn ọmọ Ile ẹkọ t'ẹnu bọ orin, bi ẹni wipe awọn Maleka li o tẹwọ gba orin ni, nwọn si kọ orin na pẹlu ohun idagbere nitotọ. Adura ti gbogbo ilu nṣe fun Olulana, o ti pọju. Nitoripe t'ọkunrin, t'obirin, t'ọmọde t'agba: ibaṣe Onigbagbọ, Imale, tabi Abọriṣa; ati Olukọ, ati ak' ẹkọ, gbogbo wọn li o nrọjo adura sori Olulana ti Ijọ Brotherhood fun imọlẹ otitọ, ododo, ifẹ, ẹkọ rere, ero rere ati ti iwa rere ti o mu wa si arin wọn li akoko yi. Ọrọ ti p'esi jẹ, ko si si ohun ti a tun le wi ju AMIN! bẹni ki o ri; ati ki iwasu na le ṣe gbogbo awọn ti o gbọ ọ lõre patapata. Amin.

Ori ẹnikeji ti njẹ enia li o wule ni ọjọ na; ọjọ nla li ọjọ na si jẹ fun Ijọ Brotherhood ni ibi gbogbo, bi ẹni wipe ki Olulana ma fi ibẹ silẹ mọ ni. Omije si bọ li oju Olulana papa (*Jesu pã sa sọkun ri,*) nigbati o ri bi ọkan awọn enia na ti gb'ogbẹ, ati bi o ti jẹ wipe ọpọlọpọ ti o wa nibẹ li o sọkun, papa awọn ọmọ Ṣukuru (*School Children.*) Lẹhin na, a wọ Mọto wa si Ejirin; awọn diẹ si sin wa de Ejirin. Wére ti a de Ejirin ni a wọ "Ọkọ BAILEY." Ọkọ na ṣí ni iwọn agogo meji-abọ. Nigbati ara tù wa tan, ti afẹfẹ Langbasa fi idẹra (*Easiness*) ṣe wa ni alejo, a tun tẹnu bọ orin, Ọkọ ndún yungba pẹlu "Orin IṢỌLA;" bi eré, a gún si Ẹpẹtẹdo ni iwọn agogo meje-abọ, awọn èro diẹ si wa pade wa.

Abọ̀ re o, ará ilu. Alãfia ki a ba nyin?

---

## IROHIN ṢOKI

NIPA

### IRIN-AJO LỌ SI IKORODU.

Ẹgbẹ awọn ọdọ ni ọkunrin ti Ikorodu wọ ọkọ ni owurọ ọjọ ọsẹ, JANUARY 20th, 1924, ni Ebute Oju Olokun, li agogo meje owurọ lọ si Ikorodu, a si gunlẹ ni iwọn agogo mẹsan abọ owurọ, gẹrẹ ti a ti gunlẹ, awọn die ninu awọn ẹgbẹ yi tamọ Kẹkẹ-ologere wọn (*Bicycles,*) bi idan, nwọn si ti de ilu, awọn ti o ti wọ ọkọ ni ọjọ Satide (*Saturday*) ti pejọ de wa, afara ko si mọ, a si ti sọ fun Olọja (Ọba) wipe a nbọ wa ri on ati awọn Oloye rẹ fun pipari ede-aiye 'de ti o wa li arin awọn agbalagba wa papa ti o jẹ onigbagbọ. Lọgan, awọn Ọmọ-ẹgbẹ ti pe 'sẹ si ile Ogbẹni wa, Banjoko, a si dorikọ Afin Olọja, li aifagun lọ titi, a de Agbala Ọba: ẹsẹ ko gb' eji ni fun ero l'ọkunrin, l'obinrin ti o pejọ de wa lati wa gbọ a-ta-ta-nto-to ti a ma ba Ọba wa sọ.

Ni iwọn agogo mejila ọsan, a bẹrẹ si ọrọ lati sọ, Akọwe ẹgbẹ, Ọgbẹni Ọdẹsanya ni o kọkọ sọrọ lọ bi ilẹ, o si ki Ọba s'ọtun-s'osi ati gbogbo awọn Ijoye rẹ. Lọgan, a sọ ohun ti o mu wa wa fun wọn, tabi ti o ndun wa, nwọn si fi tayọ-tayọ gba a; lẹhin na, Ọgbẹni Banjoko, ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ tun la alaye ọrọ fun Ọba ati awọn Ijoye, papa bi irẹpọ ti ṣe le wa li arin awọn enia (ara ilu,) ti ilu wa yio si dara bi awọn ilu yoku.

Oloye Ṣobẹru ti nṣe igbakeji Apena, f'esi li orukọ Ọba ati awọn Ijoye ti o ku wipe, ki Ọlọrun ran awọn Ọmọ-ẹgbẹ yi lọwọ, ki nwọn si le ṣe ohun ti nwọn dawọle lati ṣe, ati pẹlu wipe ki a lọ ba awọn alagba wa ni Kiriyo (*Christians*) sọrọ, ki a si fi ọrọ we ọrọ fun wọn, ki ede aiye 'de tabi asọ ki o ma ṣe si li arin wọn mọ. Nitorina, gbogbo ẹnyin Kiriyo l'ọkunrin, l'obirin, ti o jẹ ọmọ ibilẹ Ikorodu. À bẹ nyin li orukọ Ọlọrun, ki ẹ ma ṣai fi ọrọ yi fun awọn ẹgbẹ yi sọ fun ire ilu wa, ati fun awọn ọmọ wa.

[*Koi li pari.*]

---


## H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials.

**Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand,**

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed

*Office*:—106, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

*Telegraphic address*:—**"FREEDE" LAGOS.**

P. O. Box 495.


---


## A Famous Old Holland Gin.

We have had the pleasure of meeting in Lagos with Mr. A. H. Abensur the Overseas Representative of a very old established Frm, Messrs. Erven Lucas Bols of Amsterdam, who have been making Gin since 1575.

We have personally tasted their Very Old Liqueur Gin and must admit that it is of excellent quality, particularly for therapeutic purposes. In these days of strife and change, it is a pleasure to come across a firm which has weathered all storms for over 300 years.


---


## FOR SALE.

One secondhand Harmonium with 4 Octaves.

*Price Moderate.*

Apply to Mr. A. ONIORISAN
c/o P. Z. Lagos.

### Si Oniwe-Irohin "EKO AKETE"

Mo bẹrẹ f'oji.

"Emọ kire." Ọlọrun ma fi ṣe wa. Ọpọlọpọ wa lode aiye lo ni igbagbọ pe adura a ma yi nkan pada atipe on sọ buburu di rere. Nitotọ ti a ba wo oniruru ohun ribiribi ti Ọlọrun ti ṣe fun awọn ẹlomiran nipa boya lẹhin iṣubu wọn ni Ọlọrun to wa busi asiki wọn, yio mu ọpọlọpọ wa gbagbọ si owe awọn Oyinbo bayi:—"*A step to failure is a ladder to success.*" Bẹni nkan rere asi ma ṣubu lu enia lode aiye lẹhin kete ti o ba bọ sinu idanwo tan. Aka ninu Testamenti titun ọrọ Jesu Kristi ninu ọgba Getsimani tio wipe:—"Baba jẹ ki ago yi rekọja lori mi, ki ṣe ifẹ mi bikoṣe ifẹ Rẹ" eyi fihan ni pe a le gba adura lọna oniruru, ṣugbọn laisi ifẹ Baba a ko le ri esi gba, nitoripe ifẹ ni Baba jẹ atipe ohun eri kan ki de ọdọ rẹ.

Anu ṣe ni lọpọlọpọ lati gbọ ti idanwo ti o ṣubu lu Owen Johnson ni ọjọ 28 oṣu tokọja, ọdọmọkunrin yi jẹ ikan ninu akọwe Ibode (*Customs*) ẹniti a gbọ pe ni akoko yi iṣẹ rẹ to ọdun merindilọgbọn (*26 Years Service*) ninu iṣẹ Ọba.

A fẹ ki awọn ọkawe *Eko Akete* mọ daju pe a ko fi ọrọ wa yọ ọgbẹni yi, ṣugbọn ohun ti afẹ tọka si ni ọrọ Ọlọrun to wipe. "Ẹni to ba nṣe rere ki o ma ṣe niṣo, ẹni to ba si nṣe ka ki o ma ṣe niṣo ṣugbọn emi nbọ ti emi tere mi lọwọ mi lati pin fun olukuluku gẹgẹ bi iṣẹ rẹ. Ẹnikẹni kole gbin agbado ki o ka ere nibẹ nitorina a fẹ ki awon akọwe Ibode ṣe mẹlọmẹlọ, ninu iwa wọn iba ṣe rere ni tabi buburu, ẹniti ojin si koto, kọ ara iyoku lọgbọn.

Ẹka ẹgbẹ *Democratic Party* (Onikoyi *Branch*) a ngbọ iyin nyin, Enia ṣoro Banmẹkẹ, ọwọ yin a ran o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

AKIRIMANU.

---

### FUN IRANLỌWỌ "EKO AKETE."

| | £ | s. | d. |
|---|---|---|---|
| Ọgbẹni Danjinou Zounon Kanho ... (*Portonovo*) | 0 | 14 | 0 |
| " Adeboye Ṣolankẹ ... ... | 0 | 5 | 0 |
| " Winsala ... ... ... | 0 | 5 | 0 |
| " Y. D. Martins ... ... | 0 | 5 | 0 |
| " C. A. During ... ... | 0 | 2 | 6 |
| | 1 | 11 | 6 |


# John Holt & Co.

## (*Liverpool*) Ltd.

"Flag" Cigarettes

"Elephant" Cycles

Rudge-Whitworth Cycles

Crockery

Enamelware

Dried Fish

Flour

Sulphur

White Lime

Alum

Coal Tar

Paints

Wire Nails

Corrugated Iron

Ridgings

"Pilot" Matches.

JOHN HOLT & Co. (L'pool)

BROAD STREET, LAGOS.

*Telegraphic Address* "EBANI"

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.
(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.
ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

Time. Preacher.
9 a.m. Christ Church The Vicar
6.30 p.m. do. do.
9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi
6.30 p.m. do.
9 a.m. St. John's (Aroloya) Rev. H. V. E. Johnson
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. Peter's (Alapako) Rt. Rev. Bp. I. Oluwole
6.30 p.m. (In charge)
9 a.m. Holy Trinity (Ebute-Ero) Rev. S. J. Gansallo
6.30 p.m. do. do.
9 a.m. St. David's (Jordan) Rev. J. A. Leigh
6.30 p.m. do.

**WESLEYAN**

10.30 a.m. Tinubu (*Synod Sunday*)
7 p.m. do. „
10.30 a.m. Ereko „
7 p.m. do. „
10.30 a.m. Olowogbowo „
7 p.m. do. „
10.30 a.m. Obun Eko „
7 p.m. do „

**AFRICAN (COMMUNION)**

9 a.m. Jehovah Shalom Rev. J. F. Ogunko
7 p.m. do. „ J. A. Oke
9 a.m. Erelu Bro. J. A. Laleye
7 p.m. do. „ M. I. O.
9 a.m. Christ Church (Ebute Meta) Rev. M. B. Newton
6.30. p.m. do. Bro. W. K. Fafunwa
9 a.m. Bethel Rev. E. A. Akinola
6.30 p.m do.
6 a.m. Zion
6.30 p.m. do.
10.30 a.m. African Methodist
4.30 p.m. Bro. Samuel Ajayi

**FIRST BAPTIST CHURCH**

10.30 a.m.
6.30 p.m.
9 a.m. Araromi (Baptist) Rev. A. A. Puddicombe
6 p.m. do

**EBENEZER (BAPTIST)**

9 a.m. Rev. E. C. Alabi
6.30 p.m.

**BROTHERHOOD**

7.30 a.m. Ilupesi. Resp'table Bro. J. Roṣiji Turton
7 p.m. Prof. Adeoye Deniga

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m. Fajir Service I. A. Shitta
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Glover Memorial Hall
Lieut. Colonel George H. & Mrs. Souter
7 p.m. do.

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. T. Terrell

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi:—

EKURỌ

£16—£16 10 fun *ton* kan

EPO.

£26—£27 fun *ton* kan.

COCOA.

£18—£18 10 fun *ton* kan

---

**KANO**

EPA.

£14 15—£15 fun *ton* kọkan.

AWO (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.
Hides 5d fun lb kọkan.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

taken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

nates given for the handling of goods under any circumstances.

PRICES ON APPLICATION

TO

S. I. M. Johnson,

9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

hairs! Chairs!! Chairs!!!

For hire at Ilupesi Hall, nu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½d. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,

J. A. OSHODI,
26, OBUN-EKO SREET,
LAGOS.

---

AGA, AGA, AGA.

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

WO POKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½D.) KOBO KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,

Ogbẹni J. A. OSHODI,
No. 26, ITA ỌBUN-EKO,
LI EKO.

---

The Kaduna Store,

75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*

ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to buy always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones, which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz:—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor:—

SAM ADE: CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS:—Cash with Orders.

---

ILE OWO KADUNA,

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamo) L'Eko.

Awa ni oriṣiriṣi Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn "Ero-ija" wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 lati wa lẹnu iṣẹ yi, awọn ọja wa si to ọja o ni igba pọun (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan tabi ti pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ma gbe'ro: a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹrọ-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun ṣe ti a si tun nta lowo pọ̃, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ẹniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe ṣọwọ si Olotu Ile-owo yi:—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

---

ORIRE N'TAWO.

Domingo Olorire, Alọgbọn-agba-ni'kun (*Native Doctor*) tun gbe iṣẹ rẹ sode fun ẹnikẹni ti o ba nfẹ.

☞ "Mori lọ ma mẹwa lọ" si Ile Orire, 23, Kano Street, Ebute Mẹta, ti a nṣi silẹ ni agogo mẹwa owurọ titi di agogo mẹta alẹ lojojumọ, afi ọjọ ọsẹ.

# A. KESSLER,

7, Labinjo Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER,
The German Trading House,
Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine, as well as the Alder Foot Sewing Machines,

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for every body's house.*

**FOR SALE**

The Typewriter "Perkeo" £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware,

Descent Wristlet Watches 5h. 8/- and 5h. 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps, etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite

CHAMPAGNE per case £3. 5. 0.





# JACOB AJAYI,

*General Woollen Trade*

has on hand Woollens in endless va at 50, Dosunmu Street, Lagos

**Prices to suit everybod**

*Call now, fortune awaits you.*



## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣ oṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adam ati E iṣẹdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko: ti obirin t owo mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun kika ta, Oṣẹ Olọwọ—a Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi fẹ ẹ ni *lọwọ* ile ta a fun o, Iṣana Akpoti fun ko si bi a ti nṣe wọn, Oriṣiriṣi ọja lo wa wa, iwọ kò le ba wa ṣowo ko ma jere nitori owo poku ni a nta wọn. Owo ọja wa rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ j wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọ 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba agbe ni *Nigeria* tabi ẹhin o kọwe ṣowo yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba s

E. O. AMBẸ & BROS,
38 Moloney Bridge Street, La
(*Legbẹ awọn Oniṣowo A. J. Tangalaki*
Idumagbo, Eko.

## KNOW ALL MEN

That I, formerly known as

ISAAC AKINỌLA COLE

Builder & Contractor of No. 1, Market Street a 48, Breadfruit Street, Lagos Nigeria, desire to known, called and addressed from the first day January 1924 as

ISAAC AKINỌLA OGUNMỌDẸDE.

All Transaction, Documents, Papers etc., bea the first name remain valid.

Dated at Lagos this 24th day of December, 1923.

I. A. CO

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISH ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.